# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 280 SATURDAY, JUNE 23, 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silẹ.


LOOK FOR THE PORTRAIT OF
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Carton adopted 1916.
FASSETT & JOHNSON,
Road, London, E.C.
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and
Soreness after
Severe Exertion
General Directions for External Use
Keep away from Fire or Flame
in United States of America
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fasseit & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London.
England

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### B'O BALẸ O, B'O BALẸ ṢAWORO IDẸ B'O BALẸ A RO!

Dajudaju ko si ibiti irohin ayọ ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi ko ro de bi ṣaworo idẹ nigbati Waya de lati ilu Ọba pe Eleko jare. Gbogbo ilu lo gbojikan fun ilu ayọ lorişirişi ti o yi gbogbo Eko po, ti ọgọrọ enia si njo bi kokoro, a ko le ṣẹṣẹ sọ bi ile Ọgbẹni Herbert Macaulay ko ti gb'ẹsẹ to fun ainiye enia ti nwọn rọ lọ sibẹ pẹlu ayọ ati inudidun; nigbati obinrin arugbo-rugbo aladọrin ọdun nfo lailai niwaju awọn ọmọge ti ilu si nkun bi ojo, a ko ṣai mọ pe ayọ na kuro ni kekere.

Njẹ ilu ni lati ma reti dide Prince Eshugbayi Eleko lati Ọyọ si ilẹ yi laipẹ lọ titi. A dupẹ lọwọ Baba fun ihin ayọ nlanla yi, nitotọ enia ko dabi Allah!

---

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### ỌNA 'RE O!

Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi—Jones, M.D., ba ọkọ "Accra" ti o şi nihin ni irọlẹ ọjọ Jimọ ijẹsan lọ si ilu oyinbo—a gbọ wipe o gbọlọfẹ lọ fun igba diẹ fun itori ailera diẹ ti o wa fun un, lẹnu ọjọ melo sẹhin yi—ọna 're o!

### OWO—ORI.

A gbọ wipe Ijọba ti pin iwe owo-ori tabi iye ti nwọn o ma san fun awọn oşişẹ tabi akọwe gbogbo ti o mbẹ ni abẹ wọn, a si gbọ wipe nwọn ti ba le awọn oşişẹ abẹ awọn oyinbo Ọlọkọ-ilẹ papa lọwọ pe nwọn o bẹrẹsi yọ "owo-ori" na kuro ninu owo işẹ ti olukuluku wọn ngba ni ipari oşu ti a mbẹ ninu rẹ yi, a nki i, a nsa a, awọn Ijọba ni awọn ko fẹ mọ ẹniti o ku arara—ki a şi ma woye!

### ẸRAN EWURẸ D'ỌTA ILU.

Ni otito awọn Ijọba sofin pe ẹran ti o ba rin ni oju ọna Titi tabi ni oju opopo ti Mọto tabi Basikulu nrin ki nwọn ra ẹran na mu, fun itori jamba ti awọn ẹran wonyi le şe awọn ẹniti o ngun Mọto-Basikulu tabi Basikulu tabi lati fi aye silẹ daradara fun awọn Mọto loju Titi li awa şe ri si wipe bi Ijọba ti so ofin ẹran wọnyi ko ni laifi kan, fun ẹniti o ba nşe alabapade irufẹ jamba ti awọn ẹran wọnyi le şe awọn nkan wọnyi tabi ẹniti jamba bayi tişe ri.

Şugbọn wayi o, ewo ni ki a maşe jẹki ẹran tun jẹ loju ọna olowo rẹ ti şe oju ọna ti Ijọba şe fun rinrin awọn Mọto wọnyi? A ma mọ wipe ati ẹşin ati ilẹ Ijọba lo ni gbogbo rẹ, şugbọn ki-ki awọn ẹran mọlẹ kirakita lẹnukọnna olowo rẹ laburadi pe o di alafin Titi lọwọ, ofin bẹ ko ye wa li a tişe nsọ bayi—awọn arugbo gbogbo ni nwọn nke fun irufẹ mimu awọn ẹran wọnyi lọna bayi, nwọn si ni awọn o mọ irufẹ ofin eku ma jẹ nile, eku ma jẹ lode yi—oju wa da wipe awọn ẹniti o fi işẹ ẹran mimu le awọn ẹniti nwọn yan lowọ kọ lo fun wọn ni aşẹ pe ibikibi ti nwọn ba sa ti ko firi ẹran koda bi o jẹ ninu yara ki nwọn sa ki mọlẹ ni.

### MUSIBA MỌTO TUN DE!

Digbadigba li a gbọ wipe nwọn gbe ọdọmọde kan wọ ile-Alarun Dokita Vaughan ni owurọ ọjọ Satide ijẹjọ; nwọn ni agbako Mọto ni oluwarẹ şe ni opopo Victoria—oni ogun Mọto, ọla ogun Mọto ni opopo Victoria yi kanna, eyi ma ki o!

### L'AIYE IGẸSI TI A WA YI.

A gbọ wipe abẹşẹ kun bi ojo kan sọlẹ si adugbo Ẹpẹtẹdo, ti o nfi ẹşẹ yọ wọn loju jẹ, nigbati a gbọ bayi a ni l'aiye Igẹsi ti a wa yi, tabi nibo ni oluwarẹ şe bi on wa—şugbọn a si ti gbọ 'nisisiyi pe ọwọ ti tẹ'ẹ—ni ilu Eko yi na kẹ oju a ri, ẹnu ko ni le sọ, atunbọtan aiye.

### INA WAYA—ILU.

Ọpọlọpọ aseko ni Ina Waya—ilu (Electric Light) ma nku fun awọn ẹniti o ngba wọn si ile, eyi si mu wa lati ke fun awọn Alabojuto ẹrọ-ina yi, ni iwọn igbati o jẹ wipe loşoşu ni awọn ẹniti o ngba ina na sile nsan'wo fun awọn (Public Work Department) loşoşu ti o si jẹ wipe bi ẹnikan ba şeşi rẹhin lati sanwo na gẹgẹbi ilana ti nwọn şe

fun sisanwo ina na, nwọn ni lati wa ja kuro—ohun ti enia ba si nsanwo fun o ni lati ma gbadun rẹ nigbakugba.

Kilo ba fa sababi ti o jẹ wipe ina na ni lati ma ku lai rotẹlẹ? Nitorina awọn Alabojuto ina yi ni lati ma parọ ohunkohun ti o le ma mu idalọwọkọ titan ina na nigbagbogbo, ki işe bi ti eyiti nwọn ngba si'le ti nku ni ẹmẹwa ni ti ode nku, a si ro wipe awọn oyinbo ti o gba ina si inu ile ko jẹ gba irufẹ igba-kugba bayi.

## JAMAT MUSULUMI.

A gbọ wipe Lemọmu Ligali, Başọrun pẹlu awọn jakanjakan lọ si ọdọ Alaşẹ-ilu (Administrator of the Colony) lọjọ Tuesday ọsẹ to kọja, lati fi ọran ẹdun ati laifi ti o mbẹ ninu oku awọn Musulumi ti Municipal ngbe fun yiyẹwo han, gẹgẹbi ipinu ti a gbọ wipe nwọn şe ni Mọşalaşi ni Iọlọyi; jalankato ki işe ọran ẹni kan şoşo nwọn ni awọn oyinbo koi ti mu osi wa, bi a ba tigbọ si, ao yiu si nyin leti.

---

## KINI TILẸ NJẸ IKU.

## (*What is death*).

[LATI ỌWỌ ỌMỌ AWO]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Pupọ enia ni o ngbọ oruko iku şugbọn wọn ko mọ ohun ti o njẹ bẹ, pupọ enia ni o fayi mọ ohun ti a npe ni iku ti o jẹ pe ti o ba jaja, le gbọ iro iku nibi kan waya niyẹn o di ko ma sọ kiri, ti mo ba nri iru awọn enia bẹ nşe ni ẹrin ma npa mi titi pe nibo ni iku ko si, nibi ti enia gbe lo on nsa fun iku nibẹ ni iku na gbe ma ba a si ti ibẹ di ero sare. Njẹ ẹnyin enia mi kini jẹ iku gidi, tabi kini a le fi iku we, nibi ti a gbe nwa itumọ rẹ kiri, awa ri ka nibi kan pe iku jẹ Alejo ti ẹnikẹni ko nfẹ ko wa ki on (*An unwelcome visitor*) şugbọn ti o nwa ni tulasi bi oluware rẹ fẹ, bo kọ, gbogbo enia lo si jẹ gbese iku, nitorina ni awọn agbalagba şe ma npa lowe pe, ma fi orun yọ mi gbogbo wa lajiijọ nlọ. Njẹ ti o ba jẹpe otitọ ni eyi, kini ha şẹ ti a ki nfẹ ma murale de iku nigbakigba ti o ba kan ilẹkun, ti o ba jẹ pe, iku ngba owo ni, awọn olowo ko ni 'ku mọ, ti o ba si jẹpe, ti ipo ni awọn onipo nlanla wa ko ba si wa di oni, ti o ba si jẹpe ki a mọ iwe ni, awu, ki ni a ti nşe oku lọrun, ọgọrọ awọn enia ti o jẹ o gboji ninu iwe ko ba ti ku mọ di oni ẹloni, ati ọpọlọpọ bẹbẹ, olowo o. Iku ko ni bere lọwọ rẹ, ko to mu ẹ lọ nigbati asiko ba to, o gbajumọ ni o, o fẹntẹ, o jẹ alanu ni o ati ọlọyaya enia, awọn ẹnibẹ ni iku tete ma npa, bo jẹ alagba ni o, ni ọjọ kan wọn a kọrin igbẹhin fun ẹ, şugbọn ninu gbogbo itumọ ti a ri yi, ko tẹ mi lọrun, mo wa tun sun kaka wayi pe, iku yi eyi ti o nşe ẹgbọn orun (death which is an unwelcome visitor, is also the elder brother of sleep) ẹ ko ba bi mi, idi rẹ, şe ti enia ba sun ko tun mọ ohun ti o nlọ mọ lẹhin on, şugbọn bo pẹ titi a tun ji, bẹkọ ni ti iku, iyatọ to wa nibẹ ni pe, ti iku ba mu enia lo ko tun ni mu wa mọ a fi ti a ba tun bi, ẹ ko wa ti pe iyatọ na ta koko. Şugbọn lẹhin eyi awa rope, iku ti a nwi yi, ki nşe ohun kan ti enia tun le fi we tabi pe ju, " Ipapoda lo (A change), nitoripe bi enia ba ku, o gba ipo nla lọ sọrun ni, death is a change and also a promotion to the higher life, a ma ngbọ nigbati ti nwọn ba nka pe. Ninu Ile Baba mi Ọpọlọpọ ibugbe lo wa nibẹ. Lotọ ni orişirişi ibugbe lo wa lọrun, ibugbe awọn ole, apania, a sọrọ ẹni lẹhin, olofofo tuletule, onirikişi, olododo, ẹlẹnu didun, a buni bẹni nla oyin, ọdalẹ, pansaga a bi iyako wẹrẹ, o dinu enia, a fọ'le onile, ika, ati orişirişi iwa ba wọnyi. Gbogbo rẹ lo ni ibugbe lọrun. Lotọ awa ki nşe a yẹrun bọ, nitoripe ko si ẹniti o dọrun ri to bọ, şugbọn ero ori enia le sọ, nitorina ti enia ba ku ko ni kuro ninu ile rẹ, fun ijọ meje titi yio fi şiro işẹ rẹ laiye, lẹhin eyi lo to ma mọ ibi ti on papa ma wa, tabi ibugbe rẹ lọrun, ti awọn enia ko ba si fun laye lati şiro işẹ rẹ laiye, npa ẹkun a sun dakẹ awọn enia, wọn yio si tun tun bi sinu family na, awọn ni wọn ki ma npẹ laiye mọ, tabi abiku, iru awọn ọmọ bẹ lo ma ngbọn a gbọn rege, ni awọn enia a fi ma sọ pe, ọmọ kekere lo nşe işe agbalagba bayi, ọmọ kekere lo ma si fun ọ, ngbọn ẹni to ti wa aiye ko ma yi to kankan o, a wa sọrọ agbelebu lẹnu. Nitorina ni wọn şe ma npa lowe pe—ọmọ ko layọ le, ẹni ọmọ sin lo bimọ nitori kini, ko si ẹniti o mọ igbẹhin on, a le da iwọ iya tabi baba ni Ẹlẹmi gungun ọmọ a si jẹ ẹlẹmi kukuru—nitorina bi enia ba ma tọrọ ọmọ ko ma la, nitori orişirişi ọmọ lo wa. Ọmọ gba jẹ-nsin-mi, wa, awọn ọmọ ti nwọn ti gbagbe sori igi wa, awọn ọmọ ti nwọn ko ri ẹni bi wọn ti nwọn ti di alarinkiri wa, nitorina ẹnyin enia bi Annah ti ẹ ntọrọ ọmọ lọwọ Ọlọrun ẹ ma la, ki gbogbo ireti nyin ma di ofo, Oluwa ko sọ ni ninu rẹ.

Ani nigbati enia ba ku tan ti o ba şiro işẹ rẹ laiye tan lo to ma mọ ibugbe rẹ lọrnu, nitori kini ko si ẹniti pe mọ bo ti wu ki enia lanu to, yio ni iwa kan ti ko dara, ko si ẹniti o wa laiye yi ti ko ni buruku kan, Solomon ati David bi wọn ti jẹ Olufẹkansi to yẹn ti nwọn si tẹle Ilana Ọlọrun wọn ko pe, eyi ti o fi agbere şe işẹ ni o ni pẹrẹwu wa nibẹ, eyi ti ko fi tire mọ nibẹ nikan, to ni lẹn, a obinrin lo da to yi ẹlẹyinju ẹgẹ, ani bi enia bi ko pa Uriah nitori obinrin rẹ, ẹnyin ti ẹni bi ko gbajumọ, bi ko lẹwa, ẹ ko ni fẹ, ma se iranti Uriah. Iwa lẹwa, ẹwa kan ko si nibẹ, ijọ ti o ba ti gbe a be porẹ obinrin sile ni ọjọ na lati jogun aiyinoju nitoripe bi o ti wun ẹ, bẹni on wun emi

papa tabi ẹlomirnn ogo kọ ni igbanu eyi ti o tẹle igbaju di òwó wọn ojojumọ ko ma ye nyin. Ani ṣe lẹhin ti ẹni to ba ku ba ti ṣiro iṣẹ rẹ laiye tan ti o si mọ ibugbe rẹ laiye, lẹhinna la tu ma ran pada waiye lati wa pari iṣẹ rẹ, bẹni yi ma lọ, ti yio si ma bọ titi opin aiye. Njẹ ti ko ba si iku, to ba jẹpe ọmọ gbogbo wa fẹ la nbẹ njẹ gbogbo wa a ko ni fẹ le ma lara wa mọlẹ koja bayi, bẹni a fẹ iku ṣugbọn a fẹ ma bimọ. Awọn agbalagba ma npawo kan pe Were dun wọ lọja ko ṣe bi lomọ. Tani ma ri ararẹ kan, ti o nsiwere, enia lo sa bi Oramu tabi Egunnnin Ẹran tọrọ, ti a fẹ ko wa ninu ipo bẹ titi aiye-raiye, bẹni a nsa fun iku. Tabi enia wa wo lo ma wa ninu amodi fun ọjọ pupọ ti ko ni su ẹni to ntọju rẹ. Bẹni a nsa fun iku, nigbati iku tilẹ ma mu awọn ẹnibẹ lọ kinişe ti ara fi nta wa ti o ba mu enia ti iru nkankan bẹ ko ba ja lẹ, eti ibẹ wo daradara, ẹ o ri pe Oluwa ti ṣe iṣẹ rẹ la ṣe pe, awọn kan ma nso pe ti enia ba ku a lo joko sọwọ ọtun Baba, enia kan, ko joko sọwọ Baba kankan titi opin aiye ma fi de, nigbati o ba ti ṣe kan la ṣe yọri, o tun npada bọ wa ṣe iyoku, titi o ma fi pe, nijọwo l'enia ma rin pe wa yio, ẹnyin ara iwọ osika, ole, alarankan, Mamy fly Daddy fly gbogbo—o dọrun fun nyin. Bẹ sere ẹ o ba. Ẹnyin ogbogi ninu iwe ẹ ba mi jẹdodo ọrọ kekere yi.

"A WORD IN SEASON."

Use your money while you 're living
Do not heard it to be proud
You can never take it with you
Their is no pocket in a shroud.
Glad can help you on no farther.
Than the Grane yard where you live,
And, though you are rich while living
You 're a pauper when you die.
Use it, then, some lives to frighten,
As through life they weary plod :
Place your Band Account in heaven
And Grow rich toward your God.
Use it wisely ; use it freely :
Do not heart it to be proud,
You can never take it with you.
There's no pocket in a shroud.

Ọrọ re o ẹnyin olowo ti ẹ ko fẹ na, nigbati iku ba de, tulasi ẹ o fi silẹ. Ẹ o si fo lọ, nitoripe on ko ọrọ jọ ko mọ ẹniti yio ko wọn lọ. Abọ mi re o.

Emi ni tiyin nitotọ,
ỌMỌ AWO.

## Ẹ Ṣ'ASALATU F'ONIṢẸ ỌLỌRUN.

*SALALAHU ALAIHI WASALAM !*

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Nigbakugba ati ni oniruru ọna ni awọn Musulumi nṣe asalatu fun Anobi wọn—oniṣẹ-Ọlọrun ani Anọbi Mọmọdu ; laisi tabi-tabi Anọbi Mọmọdu ṣe iṣẹ nla ni aiye, gẹgẹbi awọn Anọbi miran iyoku bi Musa, Buraimọ, Dawuda, Sumọla, Yisa ti o ṣiwaju Mọmọdu ti ṣe iṣẹ wọn eyi ti o jọ wọn loju gidigidi, iṣẹ Anobi Mọmọdu to, o si pọju eyiti enia le ṣe asalatu fun lọ.

Ki awọn Musnlumi to bẹrẹ adura, nwọn ni lati kọkọ ṣe asalatu fun Onişẹ-Ọlọrun. lẹhin ti nwọn ba si gbadura tan nwọn ni lati tun ṣe asalatu miran bakanna, bi Mmsulumi ba ti ri aye to tabi bi ọrọ ẹsin ba ti le lọkan rẹ si, bẹni o fi nṣe asalatu ti a wi yi fun Anabi Mọmọdu ko si Tira kan ti o wipe nwọn ko gbodọ ṣe asalatu ju iye igba kan lọ, bokanran eyi, a tun ri Tira ati Alukurani ti o jẹri papa si eyi pe Ọlọrun Rẹ papa ati awọn Mọleka nṣe asalatu fun Onişẹ-Ọlọrun bẹni a si ka pe Musulumi ti o ba nkirun ti o ngba awẹ, ti o nyan Sati nigbagbogbo, ti o nṣe gbogbo pẹpẹfuru ẹsin Islam ti ki iṣe asalatu lorekoreko fun Anabi Mọmọdu dajudaju gbogbo ẹsin ati igbagbọ rẹ akibo ni.

Ẹnti ọkan rẹ balẹ daradara ti aye mbẹ fun to, ti alafia ara si mbẹ fun pelu le ṣe asalatu ni igba talatin lati owurọ di alẹ, laulafia ni ko si haramu nibẹ.

Orişirişi ẹsin lo mbẹ ni aiye tabi oniruru ni a le gba fi sin Ọlọrun ; ninu ẹsin awọn Kiriyo, a le ka to orişi mẹdọgbọn ninu rẹ, nibẹ ni Etiopia, Ologun Igbala, Aguda, Serafu Igẹsi ati awọn orukọ ẹsin miran gbogbo wa, Anabi Issa tabi Jesu ni gbogbo wọn gbagbọ, bi o ti mbẹ fun awọn Kiriyo bẹ ni o lo mbẹ fun awọn Musulumi papa, o ni Jalailu mbẹ, Alalukurani mbẹ, awọn Ahamadiya papa si tun mbẹ pẹlu, ẹsin Musulumi kanna ni mẹtẹta yi, Anabi Mọmọdu na ni gbogbo wọn tẹle e, ṣugbọn ọna ti olukuluku ẹlẹsin fi nsin Ọlọrun ṣiwaju ati nisisiyi lo tọ suna, ṣugbọn awọn ara wọn a ma ja ara wọn ni koro pe ọkan lo tọ suna julọ—igbagbọ ti awa ni pe Ọlọrun lo mọ ẹniti o nsin On ni iwọn igbati o ba ti jẹ wipe, Allah ! Allah ! ! kanna ni gbogbo wọn jumọ nwi

Ninu ẹsin ti awọn kiriyo awọn Igẹsi le ma sọ wipe ti wa lo dara julọ, awọn Aguda le ma gbogun rẹ le ri pe ti wa da wọn loju to ada, bẹni awọn Salvation Army ti nwọn nfi ilu Bẹnbẹ oyinbo ati awọn Isholarian ti nwọn nlu ilu Batakoto ati awọn Etiopia ti nwọn nfi Gita ati Agogo-aja ṣe wasu ati

awọn Brotherhood le ma yanga pe ti wọn lo tọ suna, ko si alamọla kan ti o ma ni t' on ko yi.

Nipa ẹsin awọn Musulumi mẹta ti a ka fun nyin, dajudaju nwọn a ma ta kanrangba si 'ra wọn pe ọkan lo dara, ọkan ni ko dara—Awọn Oni-Jalailu nwọn nke Alukurani ti nwọn ba fẹ ṣe wasi ṣugbọn nwọn ki i fi ṣe wasu ninu rẹ bikoṣe Tira Jalailu—awọn Alalukurani ẹwẹ si nsọ wipe Alukurani nikan gede li awọn mọ lati fi ṣe wasu, nipa eyi awọn Oni Jalailu npe wọn ni oni-ṣakiti ṣugbọn awọn Alalukurani gba suna ebu-o-so ! sori nwọn ko bikita ebu ti nwọn fi nbu ara wọn, nitori awọn Alalukurani awọn Oni-Jalailu ni kalaṣaihu ; awọn Ahamadiya kẹ ti nwọn ba fẹ kirun ti wọn, nwọn a fi owọ si aiya, ṣugbọn awọn Oni-Jalailu ati Alalukurani nsọ wipe eyi ko tọ suna ninu ẹsin Islam, awọn Ahamadiya si nsọ wipe ko si Tira ti o kọ eyi ati pe awọn ẹniti o nṣe bayi pọ ni ilu Mọka ju awọn ẹniti ki iṣe bẹ lọ. bayi ni ẹsin olukuluku ti ṣe mu ariyanjiyan dani, eyiti a fi sọ Ọlọrun lo mọ ẹniti o nsin on.

Orukọ pupọ ni a le da ni orukọ awọn enia nlanla gbogbo ti o ti da orişirişi ẹisu silẹ, ẹsin ti ọpọlọpọ ẹda si gbagbọ titi di oni yi, ani nwọn ẹniti a le pe ni Anjọnu ninu ẹsin igbagbe ti Kiriyo ati Imale, eyiti awọn ọpọlọpọ enia ni gbẹgbẹlẹ iwọorun nihin le ṣai mọ orukọ wọn tabi orukọ gbongbo ẹsin wọn.

Ṣugbọn ti a ba darukọ Anabi Musa Buraimoh, Issa ati Anọbi Mọmọdu yio tete ye gbogbo enia, gẹgẹbi orukọ Ọbatala, Agbigba, Ọṣun, Ogun, Ṣango, Ọya, Ọrunmila ati awọn oniruru 'mọlẹ omiran ti nwọn nsin ti tete nye awọn Babaloriṣa, ti o si ndun yungba bi oyin leti wọn.

Ẹni Ọlọrun ni Anọbi Issa apẹrẹ imọ Ọlọrun ni ododo li o si fi silẹ lọ, orukọ rẹ si ndun ni Ṣọṣi ni ijọmẹjọ-mẹjọ, bẹni yio si ma dun lọdọ wọn titi ọjọ Alikiyaomọ, ṣugbọn a gbọ wipe awọn Ahammadiya sọ wipe o ti pada wa si aiye ni iwọn ogoji ọdun o le melo sẹhin, on ni Mahdi ti o dide ni Qadian, gẹgẹbi ireti ọpọlọpọ awọn Musulumi iyoku ṣugbọn ariyanjiyau mbẹ ninu eyi de Mahdi na ni yio si yọ ida ti yio fi dumbu Dajal, tọtuntosi lo mọ itumọ pataki ti o mbẹ ninu eyi nitori awa ki iṣe Imale, bẹni a ki isi iṣe Kiriyo—ẹni igbagbọ ni wa, a mọ Bibeli a si mọ Kurani, ko si Kiriyo ki Kiriyo tabi Musulumi ki Musulumi ti o le ni o ku ọna ti a ma gba, dajudaju a o ma ta a lọmi ni Ọlọrun mọ !

O di edegbeje ọdun o le mejidinlọgọta ni aseko yi ti Amina fi ori Anabi Mọmọdu sọlẹ ni ilu Mọka, orukọ baba rẹ njẹ Abdulai tabi Abdallah, a le pe Anabi Mọmọdu ni ogbologbo ọmọ-orukan, nitori ko ju iwọn oṣu kan ti nwọn bi, ni Abdulai baba rẹ lo jẹ Ọlọrun wipe, ko si ni ọjọ gbọrọ lẹhin eyi ni Amina iya rẹ tun fo ṣanlẹ ti o ku,—itọju Anabi Mọmọdu nwa nbẹ lọwọ Ọlọrun ati lọwọ ẹgbọn baba rẹ ti o njẹ Aboo, olowo ni aboo yi, ṣugbọn keferi palipali ni, dipa keferi yi ni awọn Musulumi fi fun ni suna Aboo-jaili (baba-alaimọkan) di oni-oloni.

Ọrọ pupọ lo wa ni itan nipa Anabi Mọmọdu eyiti a ko le mura tan nisisiyi lati sọ, ati pẹlu ki iṣe eyi ni ohun pataki ti a fẹ sọro le lori loni—bikoṣe sisọ bi Anabi Mọmọdu ti tobi lọwọ awọn Musulumi.

Ani lati ọmọ oponlo ni Anabi Mọmọdu ti di ọmọ-orukan, ṣugbọn gẹgẹbi o ti jẹ wipe Oluwa fi eyi ṣe sababi kaku pataki fun u, o ndagba titi, o di igi araba ti owọ ọmọde ko ka mọ, lati kekere ajanaku lerin ti pọ ju ẹfọn lọ, irohin Anabi Mọmọdu bẹrẹ si gbilẹ ni ilu Mọka baba rẹ nipa si sọrọ Ọlọrun ati fi fi awọn apẹrẹ oniruru lelẹ, pẹlu ati lakaye ti o si fi nsọrọ Ọlọrun pe ki nwọn tẹle on, Oluwa lo ran on nişẹ, on si ni ẹni ikẹhin ti Ọlọrun ran nişẹ ti a ki yio si gbe ojiṣẹ pataki kan dide lẹhin on.

Nipa eyi Aboo ẹgbọn baba rẹ ati awọn isangbẹ rẹ bẹrẹ si korira rẹ nwọn si nsure iṣubu rẹ—ṣugbọn malu ti ko ni iru Ọlọrun lo nba le eşinşin bi nwọn ti nwa iṣubu rẹ kiri, bẹni Ọlọrun ngbe ga, ti o si ndabo bo.

Nigbati o ṣe Anabi Mọmọdu bẹrẹ si ni ọmọlẹhin ti o ngbọ ọrọ Ọlọrun ti o nsọ

Ẹsin ti o gbilẹ ni ilu Mọka lakoko na ni ẹsin-ibọrişa, larin rẹ ni nwọn bi i si, sibẹsibẹ kadara Oluwa ko ni ṣẹlẹ ni ti Anabi Mọmọdu jẹ.

O nba iṣẹ rere yi bọ, pẹlu bẹ na, o nsọrọ pẹlu awọn ara ilu Mọka titi lọ de ọna ilu Mọdina ati gbogbo igbereko ilu Larubawa, okiki rẹ nkanlẹ kuku jakejado ibẹ bi igbati ojo nkan kuku ni Sanma.

Nigbati o di ẹni iwọn ogoji ọdun ti o d' aiye ni o wa gbogun iṣẹ wasu yi ka 'ri gan, nipa Mọleka Jubirilla (Gabriel) ti o farahan an wi fun u pe Ọlọrun rẹ ti yan ọ ni onişẹ Rẹ lati pa ẹsin iborişarun ati lali jẹ ki gbogbo awọn ẹniti o ti mọ ọ ri tubọ si, ki awọn ẹniti ngburo rẹ tubo ma gburo rẹ si, ki o si ma pe gbolohun yi lẹnu firifiri bayi pe:—*Lailaha-ila-Allahu Allaho-aqbarr ;* itumọ rẹ ni pe kọ si Ọba kan afi Ọlọrun—on lo to bi julọ kini Aboo ẹgbọn rẹ ati awọn iyoku gbogbo ilu Mọka ngbọ bayi si nwọn fanmu sa pe ko si şişe ko si aişe pipa ni awọn ma pa a, eleyi kẹ ! ọmọ kekere ti nwọn bi ọjọ wo nihin ni yio si tun ma wa gbe ogun dide si awọn ọmọ Abdulahi ni ilẹ yi na kẹ ! Aboo ẹgbọn baba rẹ papa ndamareke pe ki nwọn fi şe ohunkohun ti ba wu wọn, ko jẹ ki papa sinmi ni ile, nwọn bẹrẹ si sọ orişirişi ọkan-o-jọkan isọkusọ si i lara li eyi ti a ko le ma kan tan.

Ninu eyi ọta Mọmọdu tunbọ npọ si bẹni o si nni ọrẹ kun ọrẹ ni ilu baba rẹ. Nigbati idamu ti nwọn nfun u papọju, Oluwa ran Mọleka Jubirilla

si pe ki o yẹra fun awọn keferi fun igba diẹ, nitori-pe nwọn nwa iparun rẹ—Anabi Mọmọdu si mura o palẹmọ awọn ọmọ ẹhin rẹ si ba kuro ni ilu Mọka ljọ kẹdogun oṣu July ọdun 622 A.D. eyi yi ni nwọn npe ni "Hijirat" tabi isalọ kuro, lati isalọ yi ni Momọdu pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ ti gba de Mọdinat ilu iya rẹ, nibiti orori rẹ gbe wa loni ti awọn Musulumi nlọ kansẹ fun lẹhin ti nwọn ba ti ṣe ẹsin "Alhdj" wọn tan ni ilu Mọka; ibiti Anabi Buraimọh fi ṣe ipalẹ ẹsin.

A ko gbọ ni itan bẹni a ko ri ka ninu Tira tabi ninu iwe-k-iwe kan pe Anabi Mọmọdu lọ si ile keu tabi ile-ẹkọ kẹko kan—o wu Ọlọrun lati fi Anabi Mọmọdu ṣe Giwa ogongo baba-ẹiyẹ lori gbogbo awọn woli ti o ti ṣiwaju rẹ ani o wu u, o fi ṣe atọpalọtọ iori gbogbo Musulumi patapata lati oke de ilẹ, ṣaṣa ni ibiti orukọ rẹ si ninu ọrọ ẹsin awọn Musulumi ati lai si orukọ rẹ ninu Tira ki Tira kan yepẹrẹ ni Alfa.

Itumọ ẹsin Musulumi Islam ti Anabi Mọmọdu da silẹ ni wipe ki a tẹriba fun Ọlọrun, ki a fi gbogbo ọran mọ Ọlọrun lọkan ki a si gba wipe ohunkohun ti o ba ṣe ni aiye yi yala rere tabi eyiti awa ka si ohun buburu amuwa Ọlọrun ni gbogbo wọn ko si eyi ti o ṣẹhin rẹ.

Kini ohun ti a npe ni Musulumi ni pe ki o gba Ọlọrun gbọ ni ododo, ki a ma sa fun laifi rẹ eyiyi ni awọn ofin ti o sọ sinu Kuran, ati jubẹ lọ, gẹgẹ bi Musulumi a ni lati ma gbadura, ani lati kirun wakati marun lojumọ, bi ọran ẹsin ba si ti gbilẹ lọkan enia si ni o fi le ma kirun si lẹhin Irun marun ojumọ, gẹgẹ bi awọn Musulumi tabi Lemọmu ti ni ọpọlọpọ iṣẹ miran ti nwọn tun fi nke si Ọlọrun lọsan, loru, lalẹ ati lowurọ.

A ko gbọdọ mu 'ti, a ko gbọdọ ta tẹtẹ, a ko gbọdọ jale, a ko gbọdọ gba owo-ele, a ko gbọdọ ṣe ṣina tabi agbere, a ko gbọdọ pania, a ko gbọdọ gba ijẹ lẹnu ọmọ-ẹnikeji ẹni, a ko gbọdọ jẹri-eke si ọmọ-ẹnikeji wa, a ko gbọdọ korira tabi ṣe keta ara ẹni, bẹni a ko gbọdọ huwa aiṣedede miran gbogbo, gbogbo iwa ti a ka wọnyi ni Anabi Mọmọdu kọ ninu ẹsin rẹ.

Loni, ọkẹ aimoye enia lo ntẹle Anabi Mọmọdu lẹhin, gẹgẹ bi ọkẹ aimoye enia bakanna ti jẹ onigbagbọ gẹgẹ bi ilana A nabi Issa—Jesu Krisiti.

Nitorina gbogbo wa ati Kiriyo ati Imale lọ yẹ ki a jumọ tẹle ilana ati ẹsin Anabi Issa, gbogbo wa ẹwẹ lo si yẹ ki a tun jumọ ṣe asalatu fun Onişẹ-Ọlọrun,—*Salalahu Alaiki Wasalam*!

(*Ko i pari.*)

**Emi ni ti nyin nitotọ,**
**KEKERE-AWO.**


## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## INA WỌLE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹfoju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

# EKO AKETE

Eko, Saturday, June 23, 1928.

## ELEKO JARE, GBANGBA ELEKO JARE, GBANGBA.

Ko si botiri ni Waya ti Ọgbẹni Herbert Macaulay ri gba lati ilu Ọba ni *Tuesday* ọsẹ yi ti o sọ ti ọrọ ajọ nlanla nipa ti jijare ti Prince Eşugbayi Eleko, ẹni Ọlọrun da ko şe farawe jare Ẹjọ rẹ ni Kotu Abẹsẹ Ọba ati pe konko owo irin ẹsẹ ti a o san fun Ẹni aiye nfẹ na ru *London* ati *Nigeria* nibi jijare ti Eleko jare ẹjọ tiantian yi yio mu ki ẹni wa na pada-wa si igboro Eko yi lati wa şe abere idirẹ ti Ijọba fi wa on lọ si Ode Ọyọ ni şaşadidi kuro nile baba on lai fun on laye arafi kan lati sọ ti ẹnu on fun Kotu gbọ nibi:

Tani ko mọ wahala nlanla ti o wa fun awọn agbagba ti nwọn nbojuto ẹjọ yi nigbati o şi wa ni riro nibi ni ọdun kẹta ọhun, titakulẹ ti Kotu si nta ẹjọ na kulẹ nigbakugba ti ọran ba wa siwaju wọn kọ lo jẹ on ?

Ko ha han gedegbe pe ọna ẹburu ti awọn ẹni mọkandilogun ijelo gba lati fi ẹlomiran sinu Iga Idunganian lọjọ kanna gan ti Ijọba mu ọmọ-onilẹ lọ si ẹhin odi; jẹ ọna abosi A şebi ọpọlọpọ nsọ isọkusọ wọn kiri bi jedijẹdi pe bi o ku irawọ kan loju ọrun egun Eleko ko le şẹyọ ni lẹyi mọ lailai şugbọn kini ijọ *Tuesday* ọsẹ yi ti jẹ o, *member*? Prince Eşugbayi Eleko mbọ wa si Eko lagbara Soko lati mọ kini o ba sababi wiwa on lọ si ilẹ Ajeji wa: njẹ oju koti gbogbo awọn onimutu mutẹ, ẹsẹ wọn ko ha wọlẹ gẹrẹ nipa irohin-aladun ti o tẹ Ilu lọwọ ni ọjọ *Tuesday* ( Atalata ) ọsẹ yi bi ? Nipa gibigibi ẹsẹ ti o gbojikan ni ibi yi ni ijarun, gbara ti gbogbo enia ti gbọ irohin are na fihan Ijọba ati awọn ẹlomiran pe ifẹ ti Eko fẹ Eleko kuro ni ifẹ yẹpẹrẹ; lala ha kọ ni orin nkọ ti ẹgba a mọyẹ enia lọkọrin lobiurin si njọ mukumukẹ kakiri igboro titi o fi di nkan bi agogo mẹta oru ọjọ *Wednesday* (Alaruba) işẹ ti suru ati iforiti nşe lo han fu gbogbo enia li ninu ọsẹ yi o si yẹ ki Ilu Eko dupẹ gidigidi lọwọ Olodumare fun mimu Ita dun ni ijarun nipa waya alyọ na; ọpẹ pupọ lo si t u n yẹ Ọgbẹni Herbert Macaulay fun işẹ r i b i r i b i ti Baba gbe le lọwọ ti o si şe daradara nipa ọrọ ẹjọ Eleko yi: kẹkẹ p'ohun m'awoko lenu lọsẹ yi fun awọn ti ko mọ titobi işẹ Oluwa nipa ọrọ yi, dajudaju ọsan to gbe Alumọ lọ si tun pada wa gbe Alumọ na bọ; owe Yoruba kan lo sọpe b'Ọba o pa ni, a gbọ t'ẹnu ẹni, kilo şe ti Kotu wa nibi ko ri si gbigbọ ti ẹnu Ẹni wa yi nigba'i ẹjọ na şi wa nilẹyi, şugbọn a sọpẹ pe Are Apili yi fun Prince Eşugbayi Eleko laye ati pada wa si ile fun bibere "ẹsẹ" ti o nşẹ na irufẹ bibere ti Kotu Ilẹ yi ti du lati ọdun mẹta yi wa

A kan sara si Kotu Abẹsẹ Ọba King fun suru ọpọlọpọ ti nwọn ni lati gbọ ẹjọ tamutamu yi ati fun şẹria gẹsi alailabawọn ti nwọn lo nipa dida ẹjọ na.

A ki Ilu Ẹ ku afojuba Waya ijarun Ẹ si tun ku afojusọna Eleko. Laişiyemeji a tanma pe orin ti o le di kikọ nigbati Jagun wa na ba gbera lati bọ' wale lati Ọyọ ki yio şaijẹ orin bi irufẹ eyi. :—

Eleko, o Afinju Ọba
Afinju Ọba to nf'ọla re'ra
Eleko nbọ lọna
Ọmọ Apa lo ma p'ọba o' si

---

## ENIA ŞCRO!

[ Wosika Lati ọwọ Atari Ajanaku. ]

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ f'oji,

Orişirişi enia li o mbẹ li ode aiye; bi a ko ti le fẹ ẹni rere ku, bẹni arigid'enia pọ to wọbu. Olowọ mbẹ, talaka mbẹ, alanu mbẹ, ọdaju mbẹ, ọlọgbọn mbẹ, omugọ mbẹ, oniwa-pẹlẹ onijagidijagan, onitiju, alailojnti, onirẹlẹ, agberaga, olotitọ, ole, abi'kọ, akọ'gbọn: ati oniruru ati oniwakiwa enia gbogbo li o pọ ninu aiye.

Nitotọ, enia yatọ si Maleka: iba si ṣe wipe gbo-gbo ẹda ti o wa li aiye li o jẹ ẹni mimọ, boya ki ba ti si Mọṣalaṣi tabi Ṣọṣi kanṣọṣo li arin wa. A da Mọṣalaṣi ati Ṣọṣi silẹ nitori ki a le ri aye kọ wa ni ohun ti Ọlọrun fẹ, ati eyiti O kọ—ṣugbọn sibẹsibẹ, awọn ọmọ Anabi Adamọ fẹ ọkunkun ju imọlẹ lọ.

Nigbati Alufa, ọmọ onibi-niran, ti o ngbe ile ọfẹ ti o si ngba owo daradara li oṣoṣu, ti o nbu iwa ko-jọ-ole, ko-jo-afọwọra, titi nwọn fi nyo ọ kuro ninu iṣẹ Alufa bi ẹni yọ jiga, a ko ṣai mọ nigbana wipe iṣẹ akanṣe adura papa li o de ilẹ yi—ko nṣe adura ti ologomugomu.

Gẹgẹ bi Orilẹ-ede, anu ko le ṣe ki o ma ṣe ni lati ma ri iṣubu ọmọ ẹnikeji wa bayi; ṣugbọn enia dudu melo li o ha mọ wipe ẹtẹ Awo ni ẹtẹ Ọgbẹri. Bi nkan rere ba kan ẹnikan—enia diẹ ni yio gbọ, ṣugbọn jẹ ki o ṣe nkan buruku, ki o to to iṣẹju mẹwa, eku ile a ti sọ fun ti oko; bi enia ṣe aisan diẹ, ọfọ iku rẹ ni nwọn a ma tu kakiri, bi Ọlọpa ba si jaja mu ẹnikan, tabi ki oran ẹjọ de ba ẹnikan, dipo ọrọ ikanu tabi ọrọ itunu, "O pẹ ti o ti nṣe, ọwọ tẹ ẹ wayi, mu u "re" ni o ma gbọ kakiri. Ẹnikan ko fẹ ilọsiwaju, bikoṣe iṣubu ọmọ ẹnikeji rẹ—Enia bi aparo sa ni aiye nfẹ.

Ọtọ ni akọwe Ọba, ọtọ ni akọwe oniṣowo nwijọ pe Ọga wọn ko fẹ ire ati ilọsiwaju wọn, alakara ko fẹ ki ẹlomirau din, awọn Oṣe'lu ( Politicians ) njowu ara wọn, arankan ati agabagebe Alufa miran jn ti Judasi lọ, ẹgbọn pẹlu aburo nja nitori oye Lemọmu, ọganjọ oru si ni ọsan gangan awọn ẹlomiran.

Danasungbo nlu ilu, Isobo nṣan omele; nkan kan li o ma gbẹhin ijo lamurin.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## Olusakin's Column.

### The 52nd Anniversary of the Lagos Pastorate Association.

The 52nd Anniversary celebration of tho Lagos Pastorate Association commenced on Sunday, the 17th June, 1928, with Special Services in three different centres at 6.30 p.m., as hereunder :—

Christ Church—*Preacher* Rev. W. M. Peacock, M.A.

St. Paul's Breadfruit Church :—*Preacher* Rev. M. S. Cole, M.A.

St. Jude's Church, Ebute Metta :—*Preacher* Rev. J. H. A. Ogunro.

In spite of the bad weather the meetings were well attended.

The juvenile meetings were held at the following centres, June 18, 1928, at 9 30 a.m.

(i) St. Paul's Schoolroom, *Chairman* :—J. D. Akinhanmi, Esq.,

*Speakers* :—J. O. Adeleye Esq., E. O. Okusi Esq.

(ii) St. John's Schoolroom, *Chairman* :—O. Adebayọ Ọmọlolu, Esq.,

*Speakers* :—D. O. Ọnatoye, Esq., Z. O. Ọṣọkọya, Esq.

(iii) St. Peter's Schoolroom, *Chairman*—H. P. Willoughby, Esq.

*Speakers* :—E. B. Osibo, Esq., D. B. Williams, Esq.

(iv) St. Jude's Schoolroom, *Chairman*—D. A. Bright, Esq.

*Speakers* :—T. A. J. Sanyade, Esq., J. O. Adegbore, Esq.

*Tuesday, Jnne 19*

The Annual Public Meeting was also held at the Glover Memorial Hall at 7.30 p.m., under the presidency of the Right Rev. Bishop I. Oluwọle, D.D.

*Speakers* :—S. A. Thomas, Esq., B.L., J. G. Byrnell, Esq., D. T. Ṣaṣẹgbọn, Esq., and J. M. Okuyiga, Esq.

We congratulate Rev. S. Vincent Latunde, B.A., the Hon. Secretary, and all concerned in the affairs.

---

## THE PRINCE ELEKO CASE.

### PRIVY COUNCLL ALLOWS APPEAL.

## Matter of Great Constitutional Importance.

*( Reuter's News Agency )*

LONDON, TUESDAY.

The Judicial Committee of the Privy Council consisting of the Lord Chancellor, Lord Buckmaster and Lord Warrington has allowed the appeal of Eshugbayi Eleko against the decision of the Full Court of Nigeria of the 1st January 1927 upholding the view of Justice Tew on the 15th March 1926 that he had no jurisdiction to entertain Eshugbayi's motion for a writ of Habeas Corpus on the grounds that a similar motion had been dismissed by the Acting Chief Justice on the 7th September 1925.

### Question of Grave Constitutional Importance.

The Court was of opinion that the question of law involved was one of grave constitutional importance to His Majesty's subjects throughout the Empire and declared that although by the Judicature Act the Courts had been combined into one High Court that the Court still had jurisdiction to entertain application for a writ of Habeas Corpus in term time or in vacation and it was bound to determine the application on its merits notwithstanding previous judicial findings. The same principle must apply to the Supreme Court of Nigeria.

### No Opinion Offered on Merits of Application.

The Court laid stress on the point that they were not offering an opinion on the merits of the application or the validity of the orders impugned. These were matters to be investigated by the judge re-hearing the application.

The appellant is granted costs of the present appeal and also costs in the Court below.—*N. D. T.*

[ We congratulate Prince Eṣugbayi Eleko and wish him further success. Hats off to Herbert Macauly, Esq., C.E.

Ẹru Ọba ni mo ba, Eleko. ]

---

### Births.

Madam Zenobia Kẹhinde wife of Mr. Samuel S. Oshinde of 33 Bamgboshe Street, Lagos, of a female child, on Monday, the 18th June, 1928. We understand that both mother and child are doing well.

And Madam Aṣiatu, wife of Mr. Mikaila B. Oshodi of 16, Akiyẹmi Court, Ẹpẹtẹdo, Lagos, of a Baby girl. It is reported that both mother and child are keeping fit. Ki Oluwa ko ba wọn wo ọmọ mejeji yi.

---

### Death of Mr. Gbengbeleku Johnson.

The death took place at No. 35, Balogun Street, Lagos, of Mr. John Buxtulph Didorus Johnson (popularly known as Gbengbeleku Johnson), which sad event occurred on Saturday, the 16th June, 1928.

The funeral service took place at Wesleyan Ereko Church, at 4 p.m, the following Sunday, the 17th instant. The Revs. A. N. Cole and M. O. Dada officiated and later at Ikoyi Cemetery for interment.

To Mr. Michael M. Johnson and all the families of the deceased, our sympathy. R.I.P.

Oluṣakin.

## ORI IV.

## IṢẸ.

*( Translated from "Character by Dr. Smiles")*

APA KEJI.

---

Eyi ti o damiloju gbangba ni pe, iṣẹ ọkunrin, iṣẹ obirin ni ti o ba ya ọlẹ, bi o ti wu ki nwọn to, bi nwọn la ti nwọn lu, bi o ti wu ki nwọn ni enia to, bi o ti wu ki wọn ṣe orire to, ki nwọn ni ayọ to-ki gbogbo nkan tẹ wọn lọrun, ki ọkan wọn balẹ—niwọn igbati nwọn ba jẹ ọlẹ ko le si idunu fun wọn lai nwọn ko le bọ ninu ojojo ara ati ti ọkan, ninu arẹ, ninu aisan, ninu ikannu tabi ibinu, ninu ikorira, pẹlu ẹkun, arokan, ibanujẹ, ifura, nwọn a mu gbogbo aiye ni ọta, nwọn a gba ni adura pe ki awọn ku ki awọn lọ, tabi ki nwọn ri ọna jagba-jagba kan miran mu ro."

Burron sọ ju eyi lọ lori ọrọ kana: agbare-gbabọ ẹkọ ti o wa ninu iwe rẹ ni awọn gbolohun ọrọ ti o fi pari iwe na :—

" Eyi ni ki o gba ni akọtan pe, bi iwọ ba ti nwa anfani ara rẹ si, igbadun ara ati ti ẹmi rẹ lọna yi ati lọna miran gbogbo, ma gbagbe ẹkọ kerekere yi," ma ṣe gba iwa anikanjẹ ati iwa ọlẹ ni aye. Ma jẹ anikanjẹ—ma jẹ ọlẹ.

Ṣugbọn awọn ọlẹ ko kuku fi gbogbo nkan ya ọlẹ. Ara le kọ iṣẹ ni ṣiṣe, ṣugbọn ero ori ko ya ọlẹ.

Bi ko ba gbin igbado, yio gbin oṣuṣu eyiti yio hu jade ka gbogbo aiye ọlẹ enia. Iwa ọlẹ a yọ bi iwin lokunkun a ma fẹju mọ ojo enia a si ma damu rẹ :

" Awọn irunmọlẹ ṣe ẹtọ ninu awọn ẹṣẹ wa ti a kundun ni nwọn a mu ṣe paṣan nan wa "

Ki iṣe ninu ki a pa awọn ẹbun wa ti ni ailo ni igbadun tabi ayọ totọ wa, ṣugbọn ninu lilo wọn lọna ti o yẹ. Ọlẹ ni iko arẹ ba ni ki iṣe iṣẹ eyiti ifun ni ni ara lile ati igbadun iṣẹ le mu arẹ ba ọkan ṣugbọn iwa ọlẹ a run patapata. Nitorina ni ogbo oniṣegun kan fi ka iṣẹ-ṣiṣe fun ọkan ninu awọn ọna ti o fi nwo alaisan. Dr.

Marshal Hall ni, "ko si ohun kan ti o nṣe ọṣẹ bi Ọgbanraye." Archbishop ti Mayence kan ma nsọ pe, "ọkan enia dabi ẹrọ-igbado: bi o ba da ọka sinu rẹ, a so di iyẹfun; bi o ko ba da ọka sinu rẹ, a ma ṣiṣẹ lọ bakana a ma lọ ara rẹ."

Awawi kun ẹnu ọlẹ; ọlẹ ko fẹ iṣẹ iṣe, ṣugbọn o lẹnu. "Kiniun nbẹ lọna," tabi "Oke na soro gun;" tabi "ki a ma ṣe iyọnu—emi ti ṣe ti, ko ṣe ṣe."

Sir Samuel Romilly kowe ranṣẹ si ẹdọmọkunrin kan ni idahun si asọdun alawawi iru eyi: "Gbigbe ija ti mo gbe ija ko ọ, nipa ti iwa ọlẹ ogbanraye ati iwa miran ti o nhu, ko nṣe ọrọ ere, mo si ro pe ko si ohun meji ti o mu ọ ṣe iru alaro ti o ṣe lati mu ọna ijare ju pe iwa ọlẹ ti di ara fun ọ lọ. Ero rẹ lọ bayi: Olukuluku nṣe gbogbo rere ti o le ṣe. Bi a ba ri ẹnikan ti ko ṣe, ki a mọ pe Oluwarẹ ko ni ipa ati ṣe rere ni. "Ki a gba ti aikọwe rẹ si pe o ko le kọ iwe ni; ati pe aifẹ kọ iwe jẹ nitori iwọ ko mọ iwe ni. Ko si botiri ni ọgbọn yi!—ṣugbọn ire wo ni yio ti idi eyi yọ bi gbogbo aiye ba gba!"

Totọ ni nwọn sọ pe, bi o ti jẹ pe ibiti pataki aṣiri ti a fi nmọ enia ti o ba to ọkunrin gbe wa ni ti ẹniti o mọ pe ohun-kohun ti o ba dun lati ni, a ni lati ṣe wahala ki nkan na to tẹ ni lọwọ, bẹna si ni a ma nri pe ojo tabi ọlẹ enia ni nfẹ ki nkan tẹ on lọwọ laiṣe wahala kan.

---

## ẸJỌ EṢUGBAYI ELEKO.

Awọn Adajọ ro pe ọrọ ofin tamutamu ni ẹjọ na so lẹsẹ eyiti yio ko akoran ba gbogbo awọn enia ti mbẹ ni abẹ Ijọba Gẹsi kakiri agbaiye wọn si wa pinnu pe bi o tilẹ jẹ pe bi ofin ti a npe ni Judicature Act fi aye silẹ lati da gbogbo Kotu pọ sori kan, sibẹ bi Kotu ba gba isinmi o ni lati gba Iwe Habeas Kopus, ti a ba mu wa si iwaju rẹ, ki o si da gẹgẹbi sẹria bi o tilẹ jẹ pe Adajọ kan ko da re. Wọn ni lati ma ṣe aṣa yi ni kotu nla ti Nigeria. Awọn Adajọ sọ pe awọn tẹ ki o ye ni yekeyeke pe awọn ko sọrọ lori seria ti o wa ninu Iwe Habeas Kopus ti a nwi yi tabi eyi ti o wa ninu iwe Aṣẹ ti wọn fi wa Eleko lọ. Adajọ ti o ba ma gbọ ẹjọ na ni lati wadi ohun wonyi kinikini. Awọn fi aṣẹ si pe ki wọn san owo irin ẹsẹ ti Nigeria ati ti Ilu Ọba fun Eleko.

*Nigeria Daily Times 20.6.28.*

## Ẹ MA KU ẸRU ỌMỌNIKEJI NYIN.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*

Alagba:

Mo bẹrẹ foji o.

Jọwọ gba mi laye diẹ kinun ninu iwe rẹ "Otitọ ni yio leke" lati ṣe wasi diẹ ninu ọran awọn ogunlọgọ alairiṣẹ ti o wa niln nisisiyi (unemployed roaming about the town). Nitotọ nko gbe awọn alairiṣẹ nwọnyi, ṣugbọn nigbawo ni ọrọ ti mo fi ṣe koko ọrọ mi ma nwa siwaju wa? Ngbo-burọda tabi kọsini, o jẹ ri ọmọ ti o wa ninu ẹbi rẹ ki o ma rin kiri lairikanṣekan, nṣe kọ ni inu rẹ ma dun? T' iwọ ma sọ pe ko je tẹriba. Emi ti nkọwe yi nkọ—A bi mi ninu ẹbi ti ẹnikẹni ati Oyinbo ati Yoruba ko jẹ sọ pe ka ko tiwọn kuro lawo ninu Oye gbigba. Ewo loku, ẹnikeji? Ṣugbọn larin gbogbo nwọn anu ṣe ni pe ko si ẹniti o le ṣe iranlọwọ pini (pin) fun ara ile.

Nipa ojulumọ ati alanu mo bẹrẹ iṣẹ labẹ Oyinbo onișowo ẹlu adọta șile loșu lati ibẹ nipa alanu bakanna mo bẹrẹ iṣẹ Ọba bi akọwe ti nkọṣẹ (Government Probationer) titi fun asiko diẹ ki nwọn to ta'mi si iṣẹ mi (termination of appointment nipa Entrance ko ṣe Entrance, ngbọ iba sa ni alaro lasan ma ṣe mọ.

Awọn Bachelor of Crafts nwọnyi ma wa titi di oni, ṣugbọn ọpẹlọpẹ Aunti mi ti mo fi ri iṣẹ £3 10/- ṣe labẹ Lawyer kan nisisiyi, ki sa buru titi ko ma ku ẹnikan mọ ni. Ẹgbọn temi ma wa nilẹ ti o jẹ pe bi mo ba de ọdọ rẹ nṣe lo ma wipe there is no vacancy for which you are suitable nigbakugba ti mo ba de ọdọ rẹ.

Nipari ọrọ mi, gẹgẹ bi oye ọmọde ti mo ni, emi ri pe o yẹ o si tọ jọjọ bi awọn ẹbi ba ṣe ni ohun ẹdun ọkan wọn lati ma boju to awọn irufẹ enia bawọnyi. Nitotọ iṣẹ pupọ wa lati kọ, ṣugbọn kosi boys kan ti o ma wa ni iru ipo tabi ninu ẹbi bayi ti ko ni ma wa iṣẹ akọwe kiri pe boya on le ri bi iwọn £2 tabi £3 gba loșu titi Ọlọrun yio fi pa igba da si rere ju pe ki on lọ bẹrẹ iṣẹ kikọ ti ko ni ri epinni (½) gba ni odindi oṣu mẹfa ti o ti bẹrẹ si ko iru iṣẹ bẹ. Ọrọ re, gbogbo ẹnyin ẹbi, o di ọwọ nyin, ẹnyin ni o ni aiye dun ki a wa jẹ, bi a ba si ti ṣe aiye si nipa aibikita ati ainani iwa larin nyin si iru awọn alairiṣẹ nwọnyi, o da mi loju pe Ọlọrun yio bere iwa onikaluku lọwọ arakọnrin rẹ.

Mo dupẹ lọwọ rẹ Oniwe Irohin fun aye ti o gba mi yi. Ki Ọlọrun ki o ma gbe ọwọ rẹ soke.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ARIGBỌDỌWI.

---

**Publication Received.**

A Pamphlet "In defence of the Catholic Church" being a reply to the Rev. S. C. Phillips, by Dr. Moses da Rocha, M.B., ChB.

# *Are you keeping 100 per cent of good health?*

If not, then get a bottle of "Life Tonic Tablet" made of pure yeast and vitamines which are indispensable to good health.

***3/- per bottle of 50 pills.***

Keep away from all venereal diseases by using our "Antigon Pills."

***3/- per bottle. A reliable antisceptic against all urinary disturbances.***

OBTAINABLE AT:—

## Iyin Oluwa Medicine Stores.

---

### *IJAFARA L'EWU.*

Bi iwọ ko ba le ṣe inawo aṣọ otutu fun ọmọ rẹ l'asiko yi, lọ ra Ipara Awo'gba Arun t'a npe ni 'Kaduna Balm' ni Ṣabu Sabegi ni iwaju orori Matin No. 6—Ṣile kan pere ni Otutu ode isisiyi ko ṣe farasilẹ fun.

# Advertisement.

Vacancies occur at Ijora and other Stations in Nigeria for a number of experienced boiler house engine from attendants.

Applications will only be considered from men having previous experience with high pressure boilers and high speed reciprocating steam engines.

Commencing Salary from £72 to £88 per annum, according to qualifications.

Full particulars of experience and training should accompany applications, which should be in writing and addressed to the Director of Public Works, Lagos.

---

# Attention ! Attention ! ! Attention ! ! !

FOR BUYERS IN GENERAL.

HAVE YOU BEEN AT

## IWA-JO-WA STORE, (No. 1 & No. 2)

IF NOT, WHY NOT? AN OPPORTUNITY ONCE LOST CAN NEVER BE REGAINED.

The undersigned have in Stock for sale at unbeatable—prices not obtainable else-where.

The following cheapest materials are kept in Stock.

**Rubby, Rubby, Rubby !**

*( Again and again, "Gbangba dękun" Kedere bę wo. )*

**Goldsmith Tools :—**

Pickers, of any kind or size
Plowpipes, of any kind or size
Scissorses, do.
Drawplates, do.
Brass mouldings, do.
Hand Scale, do.
Brass Lamps, do
Screw Plates, do.
Cutting and doming punches of any kind or size.
Assorted kinds of Files,
Bellows of any description

Bench Vices, of any description
Crusibles, do.
Kegs of saltpetre,
,, ,, Alum,
,, ,, Borax
Pure Silver grains, too numerous to mention.
Capentory Tools of any description
Shoemakers, do.
Sawyers, do.
Bricklayers tools of any description
Bicycle accessories do. etc. etc.

Seeing is believing;

"*Ganni ya fi ji.*" Irohin ko to afojuba.

Apply-to Proprietors D. ODUSANYA & BROS.,
*Expert Goldsmiths.*

45, Princes Street. Isalęgangan, Lagos,
20, Victoria Street, Lagos.

*Cable Address :—*
**Iwajowa Store No. 1,**
**45, Princes Street, Lagos.**

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### RẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

## WHITE'S WONDERFUL BRAIN TONC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—" WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

### Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

**When replying advertisers please mention *Eko Akete***

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

**Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.**

:o:

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.